# OBINRIN KAN TORI OKUNRIN FE PA ARA .




*AWOGBA Omode fun Giri, Eyi, Hihu-ehin, Orere. Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St., LAGOS*

ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

*TO CLEAR*

*Gents Suede Court Shoe Brown, Black & Grey Before 50/- Now 42/6*

Obtainable at :-

A. B. AKINYẸMI

*10A Moloney Bridge St*

LAGOS.

VOL. VIII No. 463. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, APRIL 14, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)

## Obinrin kan tori Okunrin fe pa ara re !

NEW YORK— Irohin kan ti a gbọ lati ilu Amẹrika ni wipe ọdọmọde obinrin kan ti orukọ rẹ njẹ Anne Mills, ọmọ ọlọdun mẹdọgbọn ni ọjọ ori rẹ, ni nwọn ri ninu iyara kan ninu Ọkọ ofurufu (Aeroplane) nitosi ibudo ọkọ Ofurufu ni Idle-wild pẹlu ẹjẹ lọrun ọwọ rẹ ati ọrun rẹ.

Ọkan ninu awọn ọmọbinrin ti o nṣiṣẹ ninu Ọkọ na l'oke ibosi ti awọn oṣiṣẹ ọkunrin fi wa fi agbara ṣi ilẹkun iyara ti Ọmọbinrin na ti mọ ara rẹ lati ṣe iṣẹ buruku yi fun ara ararẹ, nigbati awọn gbe jade ni Dokita kan towa ninu ọkọ ṣe itọju awọn Ọgbẹ to fi abẹ ifari da si ararẹ lara.

KIL'O MU YI WA?

Lẹhinti ara rẹ balẹ diẹ ni awọn bere lọwọ rẹ wipe kini ohun to fa iru eyi, ti o fi fẹ gba ẹmi ara rẹ? O si dahun wipe Ọkunrin ara Amẹrika kan ti on pẹlu rẹ ṣe adehun fifẹ ara wọn ni o ja on tiẹ.

Njẹ enia ha le ṣe eyi? o tun sọ wipe iṣẹ enia ni,

Bi obinrin ba tori ọkunrin kan ku, ẹgbawa rẹ yo nu.

VOMICURE




Egbogi atata fun obinrin ti o mbi ninu oyun, ti ko le jẹun daradara, ti isalẹ ikun rẹ ba ndun ati gbogbo aisan to ma nyọ aboyun l'ẹnu.

Kosi ewu fun lilo rẹ, ṣa ra 'go kan ki o si ma gbadun ilafia ara rẹ.

O ... Ṣọọu.—
EJIWUNMI MED. STORE
LAGOS.
ati awọn Ṣọbu Egbogi Kakiri

## Iwadi Oko,, Owo Ak'ero" To Baje

Nipa irohin agbọ-ju-gbanu ti a gbọ niti ọkọ ero, ti o ri sinu omi ni ebute Badagry, nigbati ọrọ na de iwaju Adajọ lati wadi wo wipe tani o ṣe aṣemaṣe tabi kilo fa sababi ki ọkọ na to da awọn ero ọkọ nu sinu omi.

Ẹnikini sọ pe, ko nṣe ẹjọ on. Ẹnikeji ni ko nṣe ẹjọ on Ọgakọ ni ko nṣe ẹjọ on, Ẹniti o ni ọkọ na ni ko nṣe ẹjọ on, bẹni Agbero sọ pe, ko nṣe ẹjọ on. Njẹ nigbati Agbon nṣe ti oyin nṣe oju Oloko ha ṣe wu kubọ-kubọ bayi?

A tukọ sọ pe, on ko mọ iye awọn ero ti ọkọ ko lọjọ na, ohun ti on gbọ ni wipe ogoji enia lo mbẹ ninu ọkọ enia mẹrinlelogoji ni ọkọ na si lagbara lati ko. Nigbati awọn de ebute Badagry, nṣe ni ina ọkọ ku, lẹsẹkanna o si bere si ri sinu omi.

*Adajọ* bere wipe, nigbati o ri wipe ọkọ nri lọ sile kini ohun ti o ṣe, o si dahun pe, nṣe ni on bọ si ori ọkọ on si bẹrẹ si ju panu agba enia-la sinu omi lẹhinna ni on papaa wa bẹ sinu omi nigbati on ti gba bi enia marun la, arẹ mu on ni on ba fi idi jọko si ibikan, on si nju'wọ si awọn ọlọkọ l'ebute Badagry lati wa gba enia la, Ẹjọ na koiti pari

## Oloye Yusufu Agoro Ku

AGORO ỌKAN, ARA EKO ỌKAN.

Gbukẹ ni a gbọ irohin iku Oloye Gwa-Gwa, ẹniti gbogbo enia mọ ni Yusufu Agoro on ni ẹmi rẹ gun pupọ tobẹ ti o fi jẹ wipe on ni agba ẹniti o ṣeku ninu awọn ẹgbẹ ilu Committee, ti o ba awọn ẹgbẹ Khilla ṣe ọtẹ Mọṣalaṣi Jimọ. L'ọjọ buruku na ti awọn ẹgbẹ Khilla lọ bẹ awọn Panapana lọwẹ lati bawọn fi omi ẹrọ le awọn Ilu Committee kuro ninu Mọṣalaṣi Jimọ, Ọgbẹni Agoro yi mbẹ ninu Mọṣalaṣi lọjọ na.

Lọjọ ti Ijọba ṣe ofin wipe ki a wa Ẹṣugbayi Ọba Eko lọ kuro ni ilu Eko Ọgbẹni Alufa Yesufu Agoro jẹ ọkan ninu awọn Ilu Committee ti o ngwo-ngra, ti awọn si mu Ọba na pada bọ si ilu Eko.

(Wo yoku l'oju ewe kẹjọ)

## Oloye Awolowo Mbo Wa Sile



OLOYE AWOLỌWỌ

A gbọ wipe Oloye Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ pẹlu Ọlọla C.D. Akran yio pada de sile ni ọjọ Kejidinlogun oṣu yi, ọjọ Wednesdays, yio si ba awọn Oniwe Irohin se ipade ni ọjọ Alamisi (Thursday) ọjọ kọkandinlogun.

A gbọ wipe awọn ti nṣe eto ... sile ninu Ibadan ... fi ki Oloye Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ ati awọn isọngbe rẹ ka bọ inu ilu won.

Ki Allah mu wọn de l'alafia amin.

THE NATIONAL BANK

**Of Nigeria Limited.**

Ile Ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ onisowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna ti o dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti anta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
87, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princes Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

## Alatise Ni Mo Atise Ara Re

Olotu,

Jowo gbami laye lati so itan kekere yi fun isiri awon Okawe Eleti-Ofe. Awon baba wa ni ma pa lowe wipe:-Eni to mo'yi ko mo eyi ni iku fi po laiye", ati wipe "Alatise ni mo atise ara re".

Okunrin kan wa ni igba lailai ti oruko re nje Alatise". Afoju ni okunrin yi je ti ko si bimo. Oruko okunrin yi tan ka gbogbo abule ti o fi je wipe odo re ni gbogbo enia ma npade lehin igbati nwon ba ti oko nwon de, nwon asi ma ba sire wipe "Alatise ni mo atise ara re.

Ni owuro ojo kan lehin igbati gbogbo enia ti lo si oko nwon, Asa kan nle eiye kan bo, are ti mu eiye yi nitori ona ti o ti nsare bo jin pupo, nigbana ni eiye yi ri Alatise ti o joko leba ona, o si be wipe ki o je ki on sapomo si abe aso re. Alatise sigba he. Nigbati Asa yi de odo Alatise o be wipe ki o jek on yo ifun eiye na je (nitoripe ifun ni asa nje) o si pinnu wipe on yio se ti oju re y'o fi la ti yio si riran ti o ba le mu eiye na si ita fun on.

Nigbati eiye yi gbo iru adehun ti asa se, eru ba, on na si dahun wipe bi Alatise ba le da emi on si on yio se ti Alatise yio fi ri omo bi lojo aiye re. Adehun ti eiye ati asa yi je ohun edun okan Alatise ti oro na fi mu l'omi, ti ko mo eyi ti on yio se. Alatise fi oro yi lo okunrin kan to nkoja lo, sugbon okunrin na si dahun wipe "Alatise ni mo atise ara re".

Nigbana ni alatise wa ro ori ara re omu oromo-adie kan sita fun asa na, asa na si gbe oromo-adie na lo; oju Alatise si la o si riran lesekese. Alatise da eiye na sile o si folo. Lehin igbana ni aladugbo kan fi omo re ta Alatise lore, omo na si nse abiyamo fun u. Lati igbana ni o ti di owe lati odo awon baba wa wipe:- "Alatise ni mo atise ara re".

Emi ni
Toff Solomon
(Aniseere Ogun nile)

## Iyawo Miringindin Nita Akanni

Ko si boti ri ni irohin, nigbati Ogbeni wa, Alagba J.M. Babalola fi nsin omo re Obinrin fun oko ti o si tun ngbe iyawo fun omo re okunrin. Oko iyawo elese osun ni Ogbeni Solomon Adeyemi Babalola oruko mo re ti o sin niyawo fun oko nje Adedamola Babalola

Enia po ti o wa lati Oyo Awe, Iseyin, Ibadan Abeokuta ati lati Ogbomoso. Ese ko gbeji nile oniyawo yi, Olori Onilu ti o wa lati Ilu Awe, ni Ninilola Adedokun lati Iseyin. Enia fere le ni egberun ibiti nwon fi ta eni si to buso kan orisirisi ilu bi Juju, Sakara Konkoma, Agidigbo, Aro ati Sekere l'opeja sibe.

Die ninu awon egbejegbe ti o wa sibe ni Egbe Majeobaje Awe, Egbe Ajao Egbe Wahabi Iseyin, Egbe Orepeju No I. Egbe Oredegbe No. 2 Area Council Akanni.

Die ninu awon gbajumo ati ijoye to wa sibe ni Ogbeni Alagba Dokita Maja, Oloye Ajao Otun Oyo, Sanusi Aremo Ladugbolu, Raji Dawodu Iseyin, adajo Adelabu Eero, Y. Baruwa. Olove Ojemuyiwa Iyafin Beckley ati Iyafin Dawodu Iya Oko Iyawo ojo yi ni Dorcas Orotoyinbo Babalola Iya ti omo ti a sin fun oko ni Olarewaju Babalola.

Grace Abiola Adejokun lo wa lati Zaria fun ti iyawo yi o nawo o si nora ati Iyafin Stowe. Awon iyawo a toro bosun o.

Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos

## Igbimo To Nbojuto Ina Manamana

Ise igbimo yi ni lati bojuto anfani awon to nlo ina manamana won si ni lati ma gba ibi ise ina yi ni imoran ni gbogbo ona to je mo ise won, papa nipa ilosiwaju ise na ati owo ti a nilati ma gba fun ipese ina ati awon oro miran ti a ba nfe imoran won lori re.

Igbimo na ni Alaga kan ati omo egbe medegun ti won yio se odun meta gbako awon ni wonyi:-
Alaga:- Ogbeni J. K. Buchanan, C.B.E. c/o Federal Public Service Commission, Lagos.
Omo Egbe Ipinle Ariwa :- Malam Umar Sulaiman O.B.E, M.H.C. Alhaji Shefu Ahmadu, OBE Madawakin, Kano, c/o The Resident, Kano Alhaji Isa Haruna, Bisichi Tin Co., Ltd, PO Box 7, Bukuru.
Ipinle-Iwo Orun:- O'ola A Rosiji, M.H.R. PO Box 367, 154, Ijebu Bye-Pass, Road .

(Wo yoku loju ewe kerin)



FUN

Agbara Eje ati

Agbara Okunrin

HOMMEL'S
HÆMATOGEN

Hommels Hæmatogen je egbogi ti a se ninu eje ako Malu, yio fi eje rere fun ara re se, ati irin ti yio fun enia lagbara bi Ako Malu.

O mbe ninu igo fun tita yika Sobu ile Nigeria.
Fun Agbara ise l'osan.
Fun ile a lehin ise ati ere s'ise.



Bere Lodo Asoju wa:-
ALBAN PHARMACY LIMITED
7, Victoria Street. P.O. Box 461.
Lagos - Nigeria.

**ELETI OFE**

A-NIU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS — 28, Kosoko Street, Lagos, P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS — "ELETI - OFE LAGOS" Phone 23370

VOL. VIII NO. 463, LAGOS, SATURDAY APRIL, 14, 1956.

## Jamba Oko Ero Oju Omi

Ni ọjọ Alamisi (Thursday) ọsẹ tokọja ni irohin agi oju'gbanu jamba ọkọ ero oju omi ti o nko awọn ọpọlọpọ enia lọ si ilu Agbadarigi (Badagry) ṣẹlẹ ni afẹrẹ ki ilẹ to mọ, ni dede agogo mẹrin oru mọju ọjọ Alamisi ti ọpọlọpọ ẹmi awọn obinrin ati ọkunrin pẹlu awọn ọdọmode kẹkeke ṣ'ofo danu sinu omi okun Agbadarigi (Badagry).

Ito-ibanujẹ nla ni eyi jẹ fun wa, papa n'gbati ako gbọ wipe ọkọ na kọ'u ohunkohun de'pọ ti iru iṣẹlẹ buburu yi fi ṣẹ ẹ, o si mu ero pupọ wa si ọkan wa yala gẹgẹbi irohin ti a gbọ wipe nini ti nwọn fi ẹru ọpọlọpọ apo irẹsi, apoti ọṣẹ ati idi kanwun ni ọkọ na, kia ma ṣẹṣẹ tun sọ ti awọn enia ti nwọn ni kun inu ọkọ na mọ.

OJO BURUKU, ESU GB'OMIMU

Lati nkan bi ọdun kẹrindinlogun ti iṣẹlẹ jamba Ọkọ oju-omi bi iru eyi ti ṣẹlẹ l'ọna Ikorodu, eyini ni ti ọkọ Owolowo, ireti wa ni wipe awọn Olota Ọkọ ak'ero oju-omi wọnyi yio fi iwọn-tun-wọnsi ma ṣe eto ero kiko wọn pe'u ẹru sinu ọkọ ti o jẹ wipe bi ọrọ ba fẹ di ọwọ miran ti enia ko ni ero, ko si okun ti enia le mu dani fi so okun ẹmi rẹ ro.

L'ọna keji ẹwẹ, bi o ba jẹ otitọ ni nwọn ni ọkọ na ni aniken ju bi o ti tọ lọ, awọn alabojuto alafia ọkọ oju omi (Water Police) ko ha si mọ ni, tabi wọn ko ṣe ayẹwo rẹ ki o to si kuro l'ebute Eko niwọn agogo mẹsan alẹ doriko ọna alagbalugbu omi okun Agbadarigi ? ao si da ọwọ iwe wa duro bayi na titi ti ao fi gbọ gẹgẹbi awọn aleṣẹ ilu wa ba ti ṣe iwadi ohun to fa sababi iṣẹlẹ buburu yi si:

A fi wosika wa yi ba awọn ti enia wọn padanu ẹmi wọn sinu ọkọ "Owo Ak'ero" yi, k'ẹdun, ki Olodumare Ọba Ọga Ogo tu wọn ninu, ki o si mu oju kuro ninu lafi awọn ti o ku iku ṣeidi.

## Igbimo To Nbojuto Ina Manamana

(O bere loju ewe keta)

Oloye H I Osula, P.O. Box 122, Benin City Ọlọla R A Fani-Kayọde M.H.R., 38, Queen Street, Yaba Oloye D.O A Oguntoye, 21, Ijẹbu Bye-Pass P O Box 541, Ibadan

Ipinlẹ Ila-Orun:- Ọgbẹni C.O Chiedozie, St. George's College, 11, Ogui Rd., Enugu Ọgbẹni J.A. Otutubuike, P.O Box 76, Aba, Ọlọla A.O Chikwendu M.H.R. P.O. Box 85 Umuahia-Ibeku Ọgbẹni P.N. Okeke, P.O. Box 220, Onisha. Ilu Eko:- Ọgbẹni J. Ade Tuyọ, De Facto Works Ltd., P O Box 31 Yaba Ọgbẹni A O Lawson, 28 Binuyọ Street Lagos

Southern Cameroons:- Ọgbẹni S.T.A. Tochuito, P.O, Box 27, Liberty Stores Victoria Ọlọla L S Fonka, M.H.R. Sacred Heart School, P.O Nsaw Bamenda

Fun Ile Ina Manamana:- Ọgbẹni C P Thompson c/o Office of the Council of Ministers Lagos. Akọwe Igbimọ na:- Ọgbẹni J.F.G. Sykes O.B.E. c/o Ministry of the Council of Ministers, Lagos.

Igbimọ gbọdọ pejọ o kere tan gba lẹmeji lati ọdọ gbogbo enia fun ilọsiwaju iṣẹ ina manamana ati gbogbo ọrọ to jẹ mọ iṣẹ na. Idannu Igbimọ yi lati le ma ri irufẹ imọran yi ki a si ma mu wọn wa si iwaju Igbimọ. Ṣugbọn ohun ti o ba jẹ mọ alebu ninu ipese ina manamana lati kẹkọ lọ si ọdọ awọn oṣiṣẹ to wa nitosi yin ti ẹ ko ba ri itẹlọrun gba lo ṣeṣẹ wa kan igbimọ.




**Blackpod**
**Capsid**

**Ki o le pa'no arun ara igi Koko wonyi, Ma lo:—**

ẸRỌ TI A FI NFỌN EGBOGI SARA IGI KOKO

**Mysto Spraying Equipment**



Eyiti oni Ontẹ MYSTO MODEL NO. 159
Galọnu mẹta ni omi egbogi to ngba, ẹrọ l'o nfọn omi rẹ,

Eyiti oni Ontẹ "UNAMYST"
Galọnu mẹta ni omi egbogi to ngba, ọwọ ni a fi nyi ẹrọ ti o nfọn omi inu rẹ.

A le ri awọn Irin - Iṣẹ rẹ ra ti o ba bajẹ ni owo poku.

Fi ẹrọ wọnyi lo:-

egbogi ti a npe ni "PERENOX" ati "PEREPOD" fun arun Adu.

Lo "DIDIMAC" 25 fun arun kokoro miran to nba Koko jẹ

O wa ni gbogbo eka Sọbu,

**The United Africa Co. of Nigeria Ltd**
ati U. A. C, (TECHNICAL) LTD.

## Koledoye Je Oye Otun Bale

OSHODI— Lẹhin ti ọba Olusọlọ ti ilu Isọlọ ti fi Baba ẹgbẹ Oniyẹpẹ Ọgbẹni Salami Kọledoye jẹ Ọtun Balẹ Oshodi tan ni ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ keje oşu yi ni oloye titun na fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaşẹyẹ ọjọ na lọrun ni ile rẹ 1, Koledoye Street Oshodi titi ilẹ ọjọ na fi şu.

Irohin ko to amojuba ni aşeyẹ ọjọ na. Bi Ayan onilu faaji Ibadan ti nlu ti awọn alabaşẹyẹ na nlajo mọra bi kokoro ni nwọn ngbe tombila ọti gidi s'ẹnu Awọn Iyalin Adisatu Abẹbi Koledoye Wule Akankẹ Koledoye ati Sidi şe bẹbẹ lọjọ na.

Dẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaşẹyẹ ọjọ na ni F. O. Okuntọla awọn Ọgbẹni Y. Ayinla Disu Salami Aderibigbe Suberu Atanda Kanşilo Lawal Oluwo ewọn Iya afin Wule Amọpe Talwo Tawa Wasilatu ati Saulihun Babs Ọlamijuti-wọnlọ Disu.

Oye amọri o

na, Aşoju awọn ẹgbẹ ti o nşe ifihan yi sọ wipe gẹgẹbi awọn ti o wa woran lakoko ibẹwo yi gan ti pọ to, bẹ ni awọn enia nya pẹlu itara lati ri ifihan na.

Ninu wọn ni a ri awọn ọmọ ile iwe ti wọn wa lọwọlọwọ, awọn miran si nwa bi ẹnikọkan. Ọpọlọpọ ni o nduro fun ifihan ti ọsan ti a ti fi silẹ fun ifihan aworan nkan ti o jẹmọ ilẹ wa. Ọpọlọpọ awọn ile iwe ni a ti kọ iwe ẹbẹ ki wọn le ni anfani lati wa nibi ifihan ti a ya sọtọ yi, ẹ gbọn aye ti ba pupọ. Eto wa nilẹ nisisyi lati fi akoko kun ifihan ti o wa nilẹ tẹlẹtẹlẹ ki awọn ile ẹkọ wọnyi le ri aye ni owurọ.

## Ministry of Education. Western Region

Registration of Private Institutions.

SECT. 38 of the W. R. EDUCATION LAW, 1954.

The Commercial Schools named below have been registered as private institutions by the Registrar of private institutions appointed by the Minister of Education in accordance with Section 38 (1) of the Western Region Education Law :-

1. Ijebu-Ode Commercial College, Ijebu-Ode.
2. Thomas Marshall Memorial School of Commerce Iebu Bye- Pass, Ibadan,
3. Ebenezer Commercial School (formerly Abeokuta Commercial Academy), Reservoir Road, Abeokuta.
4. Abbot's Business and Secretarial Training Institute (Abbot's Institute), Sapele.

2. It should be noted for public information that :-

(1) Registration does not imply approval.
(2) No Commercial School in the Western Region is, at present, approved by the Ministry of Education.
(3) No commercial school in the Western Region is, at present, in receipt of Government grant - in - aid.
(4) Internal Certificates of the above named institutions are not recognized by Government.

3. The attention of proprietors of Commercial Schools in the Western Region, which were in existence before 1954 but not yet registered, is directed to Western Regional Notice No. 295 in Gazette No. 20 of 5/5/55, and to Section 42 (2) of the Education Law, 1954.

## Irohin Ilu Oyinbo

Nşe ni awọn ero nya bi omi ni ilu Lodon lati lọ wo ifihan ti wọn nşe ni ibiti a npe "Iperial Institute" nipa ajo ilẹwọ ọba Elizabeth ati ọkọ rẹ ti wọn şe wa si ilẹ wa. Ninu ifihan yi ti yio pari ni ọjọ kẹdọgbọn oşu yi, wọn ti şe eto pataki fun ifihan ori şirişi aworan ti awọn aşoju iwe irohin gba ni akoko ibẹwo


## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS PAINTS, DISTEMPERS, SAFES Etc.
Just Write, Call Or Phone 21372

IKORODU TRADING COMPANY

20/28 BALOGUN STREET (P. O. BOX 395) LAGOS AND NEW COURT ROAD, IBADAN



## Sobu To Dara Lati Lo Ra Oja Ni

SOBU CO-OP.

·X. Lo ra gbogbo ohun ti o ba nfe ni Sobu Co-op bi o ba fe ohun to dara bi ohun jije, mimu, abomafo ati awon ohun elo ti a fi nko'le ni owo poku.

·X. .Awon Osise wa yio da o lohun kia kia pelu owo ati iteriba.

·X. Egbe yi ko wa ere, ohun ti nwon nfe ni lati te onibara lorun.

Egbe yi mbe nilu re - lo wo egbe na loni, iwo yio si ri anfani re.

Ile ita'ja wa mbe ni:—

53. Idumagbo avenue, Lagos. 6. Old Yaba Road, Ebute Metta,

Agodi ati Ogunpa, Ibadan, Ilesha, Akure, Benin City, Ilaro, ati Kakiri Ilu

## Western Region Production Development Board

The Board invites applications for a few Vacancies in the following grades :-

(a) AGRICULTURAL UNIT MANAGERS
£660 x 42 - £1, 070: £1,100 x 55 - £1,320.
(plus expatriation pay, where applicable as follows):-
£660 - £868 (basic) - £180
£902 - £1070 " - £240
£1100 - £1320 " £270

(b) AGRICULTURAL ASSISTANT UNIT MANAGERS.
£600 x 30 - £750.

(c) AGRICULTURAL SENIOR FIELD ASSISTANTS.
£468 x 24 - £564.

(d) (i) FIELD ASSISTANTS GRADE I
£231 x 15 - £336; £354 x 18 - £426.
(ii) FIELD ASSISTANTS GRADE II
£153; £159 x 12 - £201.

In every case poi t of entry into scales will depend on qualification an experience.

QUALIFICATIONS FOR (A)

A degree or diploma in agriculture plus several years field experience including labour control. Specialised knowledge of Cocoa and Oil palm would be as advantage. Successful applicants will be required to take charge of large plantations and must be competent in all aspects of plantation management.

QULIFICATIONS FOR (B)

A diploma in agriculture from any recognised local or over-seas institutions, familiarity with all aspects of plantation management or sound technical training in agriculture backed by several years of wide experience, in all aspects of plantation management.

QUALIFICATIONS FOR (C)

Senior Cambridge School Leaving Certificate or its equivalent and in addition a diploma from the local Schools of Agriculture and several years of field experience, including control of labour keeping of farm records and writing reports.

QUALIFICATIONS FOR (D)

Senior Cambridge School Leaving Certificate or its equivalent plus technical training in a recognised local Agricultural School. In the case of (d) (i) some years of field experience is essential.

Applications in applicant's own handwriting should be fowarded to

The Personnel Secretary,
W. R, P. D. Board,
Secretariat, Ibadan.

to reach him not later than 30th April, 1956.

Only applications of those selected for interview will be acknowledged.

## Idahun Si Ibere

OLOTU

Jọ, gba mi laye lati tumọ ọrọ ti Ọgbẹni wa Lemọmu Ajakuta kọ sinu Eleti - Ọfẹ ti Satide 24/3/56 Itumọ temi niyi:-

Baba alabamẹta (iyẹn ni ọkunrin ti obi ọmọ ti orukọ njẹ Alabamẹta) ọkunrin yẹn lọ ba baba Talabi pe Barbar lati wa ṣe gbajamọ (Iyẹ ni lati wa fa ri) fun. Baba yẹn si yọ abẹ ti oni (Copper) ni idi o fi ṣe gbajamọ na, ṣugbọn oruka baba Ọbẹ na bọ si abẹ ẹwu baba ti o joko lẹhin baba alabamẹta.

Mo dupe pupọ lọwọ Olotu. Ọkọ ijọba ko ni ṣa yin lẹsẹ o (amin). Mo ki Lemọmu na. Ṣugbọn ma fẹ ki o tẹ Itumọ awọn ọrọ na jade o.

Gbagba ni enia gbaruku ti oloye Igbaruku lẹhin ti awọn ti Igba ademu lọwọ wọn, ọpọ awọn gbajumọ ti o fẹ fi oju jẹ dodo iran na, nu igba, wọn gun ori ọpẹ lọ, nigbana ni wọn rii wipe igba lo mbẹ ninu igba elomiran (wọn wa ri pe igba "Ikan, eso kan ti nwọn ngbin ni oko" lo wa ninu igba calabash ẹlomiran) ni soki, igba oloye igbaruku tu wọn lara ju igba ti oloye gbagba-kunugba lọ. Itumọ ni kukuru asiko ti oloye igbaruku dara o si osan wọn ju igba ti oloye gbagbakunugba lọ.

J. Olu. Fr d,


## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ e wa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE
*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*

O wa lọdọ :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10. VICTORIA STREET, LAGOS

## FUN FIFO EHIN FUNFUN DARA-DARA ATI IGBADUN ENU




**Ma Lo Egbogi COLGATE Chlorophyll Ti A Fi Nfo Ehin.**

Ma fi egbogi Colgate Chlorophyll ti a fi nfọ ehin fọ ehin rẹ nigba gbogbo. Iṣẹ iyanu rẹ ko mọ lori ki ehin rẹ ma bajẹ, ki o mọ, ki o si fun-fun nikan, o tun npa kokoro ehin, ko si ni jẹki akokoro yọ'nu.

Ri daju pe o nlo 'egbogi Colgate Chlorophyll ti a fi nfọ ehin nigba gbogbo. Egbogi alawọ ofefe ti nbo bi oṣe.




gere egbogi ti Colgate alawọ ofefe ti a fi nfọ ehin

# EHIN DIDUN PELU IRORA

Ona bibọ lọwọ irora?

Njẹ iwo mo pe ọkan ninu ohun ti o na sababi ẹhin didun ni Kidinrin?

Bi ohunkohun ko ba ṣe Kidinrin wa nwọn a ṣẹ gbogbo eri kuro ninu ẹjẹ ki gbogbo ẹya ara wa le ma ṣiṣẹ dede nigbati Kidinrin wa ba nṣe tikọtikọ, ti ko si sişẹ dede, gbogbo eri a wọjọ sinu ẹjẹ a si ma a mu ki ẹhin dun ni.

Egbogi onirodorodo fun gbigbemi ti Ọgbẹni De Witt ṣe jẹ egbogi atata a t i atamatase ti o nmu ki ẹhin dun ni ṣaiọ biabia nipa titun ẹjẹ ṣe ati nipa mimu irora ati alafia ba ẹnikẹni ti ẹhin didun na mba ja.

O san ki ẹniti ẹhin didun mba ja tete fi egbogi ti a nsọro rẹ yi ko loju fun ati ba le jẹ igbadun aiye jupe ki a fi dagunla ki o si ma di ẹni bẹ bẹ lọwọ lẹnu iṣẹ rẹ ati ni igbesi aiye rẹ.

Egbogi De Witt jẹ egbogi ti a ti nlo lati aiyebaye wa, titi o fi di oni yi ko mba wiwo ẹhin didun san ti ẹgbagbeic enia ti o ti lo De Witt lo nkan sara si fun jijẹ bi idaa rẹ. Ntori idi eyi, ogunlogo iwe ni nwọn kọ sowo siwa lati fi dupẹ fun ore ribiribi ti De Witt nṣe fun won. Lo si le tita egbogi ki o lọ ra tirẹ loni fun lilo altori ijafara lewu.



A se De Witt's Pills nipataki fun wiwo ehin didun, irora orikerike lotanlatan, ibadi sisanni.

A fowo soya pe De Wett's je ojulowo egbogi, gbogbo ohun elo ti a si fi se lo pe perepere ti awon alase ilera si kan sara si pe ko si kolofin kankan nipa re.



DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles




Aworan oke yi niti omidan Sylvia Ribeiro ti ilu Cape Coast ni a nwo ti o nmu ngi fi nwọn gbẹ fun ib'atupa le dani ubi af'han awọn iṣẹ ọwọ ti nwọn ṣe ni ilu nla London.

Aworan enu to lọ ṣe ahẹṣn af'han iṣẹ ọwọ ti nwọn ṣe yi le ni ẹgbẹ-gbẹrun enia.



Aworan yi niti ọkan ninu awọn marun to sare ibuso kan larin iṣeju merin ti orukọ rẹ njẹ Brian Hewson. on l'o ntun okun fila ekeji re se ti a nwo yi.

Brian Hewson jẹ oniṣẹ aran'ṣọ ninu iṣe awọn ọmọ Ogun o si ti yege pupọ ninu ere sisa kakiri ilu awọn Oyinbo.



Aworan yi niti ọmọ ogun ... ti ... Norty Bagmann ... (Printing ...) ... Accra Gold Coast ... Mono-type ... Orişirişi ... fun ... ọwọ ... ya ju ọwọ lọ, ki ko lati lo wọn ni ohun pataki fun awọn ọmọ ikọṣẹ.

TỌWỌ
Cyin Aladun
Lyons Ice Cream
O Nmu Okan Tutu, O Nmu Ara Le
O dara Pupo.
A Nta Ni Idi Kọkan:— Kọbọ Merin, Sisi, ati Ṣile Meji.

| | |
|---|---|
| Big Vanilla Bars | 4d |
| Choc Ices | 6d |
| Family Bricks | 2/- |





## Oloye Yesufu Agoro ku

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Lọjọ ti awọn nda owo jọ lati fi kọ Mọṣalaṣi nla kan nibiti gbogbo ara Eko yio gbe ma lọ kirun Jimọ, Alufa Agoro jẹọkan ninu wọn.

Lọjọ ti edekoyede bẹ silẹ larin ijọ Musulumi pẹlu Lemọmu Braimoh, alufa Agoro mbẹ nibẹ. Melo lao ka ninu chin adepele. A gbọ lẹnu awọn agbalagba wipe, ko si Alagba nilu Eko loni ti ọjọ ori rẹ to ti Alufa Yesufu Agoro, a si gbọ wipe ọdun ori rẹ le ni Ọgọfa (120) Ẹnit a le pe ni sowọ anna pẹlu rẹ ni Ọgbẹni Bakare Sogunro ni Ebute mẹta.

Bi a ba wipe ki a ma pitan Alufa na aye ko ni gba. Ina lilahi waina ilaihi rajiun.

Ki Ọlọrun f'ori jin Oloye Yesufu Agoro Giwa.

## Enmo Ki Leyi o ?

IBADAN—A gbọ wipe ni alẹ ọjọ Wednesday nilu Ibadan ni ọkunrin arugbo kan lọ ba adajọ tantun Ọgbẹni J.I.C Taylor ti o ṣeṣẹ bẹrẹ iṣẹ nilu Ibadan pẹlu oruka ogun (juju) lọwọ rẹ to wa fiṣe idẹruba fun adajọ wipe ki o da ọdaran kan ti awọn nṣe ẹjọ rẹ lọwọ silẹ.

Adajọ fi eyi ṣe ikilọ fun gbogbo enia wipe iru iwa bẹ ko tọ suna rara.

OTITO NI IGI NSOWO BI ?




Beni, be si ko....

Ṣugbọn bi iwọ ba jẹ ọkan ninu ọpọlọpọ awọn agbe agbin Koko ni Naijiria, dajudaju iwọ yio gbẹkẹle alafia igi KOKO rẹ fun owo.

Dabobo igi Koko re ati owo re pelu egbogi Koko oni FOUR - OAKS. O ti le ni adorin odun ti a ti nfi Afon - ogun to daju yi pa'na arun adu ati awon Kokoro to mba Koko je.

Ao ri awon Egbogi KOKO oni FOUR OAKS yi ni Sobu egbe Onisowo Cooperative Supply Association tabi Cooperative Produce Marketing Society tabi Union.

COOP
WESTERN NIGERIA

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street, P. O. Box 467 LAGOS Phone 1390